# AWỌN ANFAANI IGBALA

**Romu 5:1-21; 6:1-23**

**ẸKỌ 384 – FUN AWỌ ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Ṣugbọn Ọlọrun fi ifẹ On papa si wa hàn ni eyi pe, nigbati awa jẹ ẹlẹṣẹ, Kristi kú fun wa" (Romu 5:8).**

## Ile-iṣura Ọlọrun

Ẹyin ọmọkunrin ati ọmọbinrin ni Ile-ẹkọ Ọjọ Isinmi ti Ọdọ, njẹ ẹ ti ka ẹkọ wa yii? Njẹ ọrọ Paulu Apọsteli si awọn ara Romu ha ja mọ́ nnkankan fun yin bi? Tabi awọn ọrọ ori-iwe meji yii ha ṣoro fun yin bi? Ẹ jẹ ki a gbiyanju lati kọ́ ẹkọ wọnni ti Jesu ba wa sọ ninu Ọrọ Rẹ̀. A ka ninu ori karun-un ẹsẹ keji pe "Awa si ti ri ọna gbà nipa igbagbọ́ si inu ore-ọfẹ yi." Ẹ jẹ ki a fi ọkan ṣe aṣaro pe a ṣilẹkun a si wọ ile-iṣura kan ti o kún fun wura ti a ko i ti fi rọ owó lọtun losi ati ọpọlọpọ iṣura. A si le kó iyekiye ti a ba fẹ ninu rẹ̀. Agbọn kekere kan ni iwọ ha mu wá tabi ọpọlọpọ ohun elo ti o le fi iṣura kún? Ẹ je ki a ranti pe, "Awa si ti ri ọna gbà," eyi nì ni pe a ni ẹtọ lati wọ inu ile-iṣura Ọlọrun lọ ki a si gba awọn ohun rere lọwọ Rẹ̀.

Awọn eniyan wa ti wọn ki i nireti lati ri ohunkohun gbà lọdọ Ọlọrun, nigba ti wọn ba lọ si ibi-pẹpẹ adura; lai si aniani ohun ti wọn n ri gbà ko to nnkan tabi ki wọn má tilẹ ri gbà rara.

## Ifẹ Nla Rẹ̀

Oore-ọfẹ Ọlọrun ni ifẹ nla ati ojurere Rẹ̀ si eniyan. Eniyan ko ṣe ohunkohun lati fi lẹtọ si fifẹ ti Ọlọrun fẹ ẹ; ṣugbọn nipasẹ Kristi, O fi ifẹ nla Rẹ̀ hàn. Bi olukuluku eniyan ba le mọ bi ifẹ yii ti tobi to, dajudaju oun yoo gbiyanju lọna kan tabi lọna miiran lati san diẹ ninu ifẹ̀ yii pada. "Ọlọrun fi ifẹ On papa si wa hàn ni eyi pe, nigbati awa jẹ ẹlẹṣẹ, Kristi kú fun wa." Ọ̀rọ naa ko si wi pe, "O ti fi hàn" ṣugbọn o wi bayii pe, "O fi hàn" -- Ọlọrun ṣi n fi ifẹ nla Rẹ̀ hàn sibẹ. Kristi kú lẹẹkan ṣoṣo, niwọn bi ẹgbaa ọdun sẹyin, O si jinde kuro ninu iboji. Ṣugbọn sibẹ lọjọ oni nipasẹ iku ati ajinde naa, ẹnikẹni ani gbogbo eniyan ni o le ri igbala kuro ninu ẹ̀ṣẹ wọn. Awọn ọmọde paapaa ti wọn ti dagba to lati mọ rere yatọ si buburu ti wọn si ni oye pe ẹlẹṣẹ ni wọn, le wá sọdọ Jesu ki a si gbà wọn kuro ninu ẹṣẹ wọn.

## Ṣiṣẹgun Ẹ̀ṣẹ

Nigba ti eniyan ba ti ri idariji ẹ̀ṣẹ gbà o ni lati "maa ṣọra ki o si maa gbadura" ki o má ba fi àye silẹ fun ifẹ Jesu lati lọ kuro ninu ọkan rẹ̀, eyi ti a n pe ni "ifasẹhin kuro ninu oore-ọfẹ." Nitori idi eyi a ni lati maa lọ nigbagbogbo – o kere tan lẹẹkan lojumọ -- sinu "ile iṣura" Ọlọrun ki a si gba oore-ọfẹ lati le bori ẹ̀ṣẹ ati Satani. Bawo ni a ṣe le ṣe eyi? Nipa gbigbadura tọkantọkan ati kika Ọrọ Ọlọrun. A o beere lọwọ Rẹ̀ pe ki O fun wa ni agbara lati sọ pe "bẹẹ kọ́" fun ẹ̀ṣẹ ati lati fi ifẹ kun "ohun-elo" wa. Ẹ jẹ ki a walẹ̀ jin gidigidi, ki i ṣe pe ki a kunlẹ gbadura fun iṣẹju kan tabi meji pere, bi ko ṣe ki a gbadura titi a o fi mọ pe Ẹ̀jẹ Jesu ti ṣàn bo ọkan wa.

## Ẹwọn Wura kan

Ẹni ti o ba ri igbala wà ni alaafia pẹlu Ọlọrun; o ni ayọ́, ireti, ifẹ, ipamọra, iwa pẹlẹ, suuru, iwa tutu, iṣoore, iwa rere, igbagbọ́ ati oore-ọfẹ. Ẹ jẹ ki a ka ọkọọkan ninu awọn nnkan wọnyii si apa kan ninu ẹwọn wura, eyi ti a fi de ọkàn wa nihin, ti a si so apa keji rẹ̀ mọ Itẹ Ọlọrun ṣinṣin. A ko gbọdọ jẹ ki ọ̀kan ninu awọn asopọ wọnyii ki o já bi kò ṣe pe ki a jẹ ki ẹwọn naa wà papọ ki o si lagbara bi a ba fẹ ki o gbé wa de opin. Bi igbagbọ bá sọnu, ẹwọn naa ti já, bi a ba jẹ ki kóko ti ifẹ ki o já, ẹwọn naa kò pé mọ́. O gbà pe ki gbogbo asopọ wọnni pesẹ ninu ẹwọn wura yii ki a to le ni asopọ pipe pẹlu Ọlọrun.

Jẹ ki ẹwọn ti rẹ jẹ eyi ti o lagbara, nitori o gbọdọ jẹ eyi ti o le gbé ẹru wuwo. Ọpọlọpọ nnkan ti o ṣoro le kọlu ọkan rẹ lati fẹ já ẹwọn naa. Iṣẹ Satani ni lati mu ki o kọ adura gbigba silẹ, nigba naa ẹwọn rẹ a di alailagbara.

Ki ni ṣe ti a ka ẹwọn yii si eyi ti a fi wura ṣe? Idi rẹ̀ ni pe wura a maa wà pẹ́. Ẹni kan ti wi pe, "Wura alailabula ki i bẹru iná." Ọlọrun le faye silẹ lati dán ọkọọkan ninu awọn asopọ ẹwọn rẹ yii wò lati mọ bi wura alailabula ni tabi bẹẹ kọ! Jobu wi pe, "Nigbati o ba dan mi wò, emi o jade bi wura" (Jobu 23:10).

Ki ni ṣe ti awọn ọmọ Heberu mẹta wọnni jade lati inu ina ileru ti òorùn iná kò tilẹ si lara wọn? Idi rẹ̀ ni pe “iná kò lagbara” lori wọn (Daniẹli 3:27). Wura kọ́ ni a fi ṣẹda ara wọn, ṣugbọn o daju gbangba pe ọkàn wọn mọ́ bi wura, Ọlọrun kò si jẹ ki iná naa pa wọn lara.

**Bibọ́ lọwọ Ẹ̀ṣẹ**

Awọn Onigbagbọ́ ki i dẹṣẹ. Paulu sọ fun wa pe nigba ti a ba ri igbala, a di “oku si ẹṣẹ.” A ti kan awọn ẹ̀ṣẹ wa mọ́ agbelebu nigba ti a kan Jesu mọ́ agbelebu. Nigba ti a bá gbadura ti a wá Ọlọrun fun isọdimimọ́, ti a si fi ara wa rubọ fun Ọlọrun, lẹẹkan si i Ẹjẹ Jesu yoo wọ inu ọkàn naa yoo si pa gbongbo ẹ̀ṣẹ run. Gẹgẹ bi Jesu ti kú ti a si tẹ Ẹ sinu iboji, bakan naa ni ogbologbo ẹda ẹ̀ṣẹ ni yoo kú a o si pa a run nigba ti a ba sọ ọkàn di mimọ́. Ẹni ti a sọ di mimọ́ di “okú si ẹ̀ṣẹ ṣugbọn bi alãye si Ọlọrun ninu Kristi Jesu Oluwa wa.” Igbesi-ayé ẹni ti a sọ di mimọ́ jẹ igbesi ayé ti o bọ lọwọ ẹ̀ṣẹ ati idalẹbi – o bọ lọwọ ẹ̀ṣẹ ti inu ati ti ode ara – nitori pe Kristi ni Ọga rẹ̀.

**“Ẹ̀ṣẹ ‘Kekere’ Kan”**

“Nitori ikú li ère ẹ̀ṣẹ; ṣugbọn ẹ̀bun ọfẹ Ọlọrun ni iye ti kò nipẹkun, ninu Kristi Jesu Oluwa wa.” Lode oni ẹ̀ṣẹ ati awọn ohun ti n mu eniyan dẹṣẹ n pọ̀ siwaju ati siwaju si i ni. Iwe “apanilẹrin” ti o lé ni ẹgbẹrun lọna ẹgbẹrun lọna aadọrun ni a n tà ni oṣu kọọkan, awọn ọmọde ati awọn ọdọ ni o si n ra eyi ti o pọju ninu awọn iwe wọnyii. Omiran ninu awọn iwe wọnyii n fi iwa buburu, ifẹkufẹ, ati ipaniyan kún ọkan wọn.

“Ẹṣẹ ‘kekere’ kan a maa fa ọpọlọpọ ẹṣẹ si i.” Alakoso ile-ẹkọ giga kan wi pe ninu gbogbo ọdun mẹẹdọgbọn ti oun lò gẹgẹ bi olori ile-ẹkọ, oun kò i ti ri ẹni kan ti iwa taba mimu ti kó lẹru ti o ṣe e gbẹkẹle lati sọ otitọ. Alufaa kan ti o ni anfaani lati bá awọn ọmọkunrin ti o wà loju ikú ninu ile tubu ti a gbé n kọ́ awọn ọmọ buburu lati di ọmọ rere sọrọ pe gbogbo awọn ọmọkunrin wọnyii ni ọmutaba, gbogbo wọn si ni ọmuti. Boya ẹ̀ṣẹ ti wọn kọ́kọ dá ni aigbọran, lẹyin eyi eke, lẹyin eyi fifa eefin taba sinu lẹẹkan nigba ti ẹni kan kò ri wọn. Ta ni o jẹ́ rò pe iru ẹ̀ṣẹ ti o dabi ẹni pe “kò lewu ninu” yii le yọri nikẹyin si ikú fifi aga iná manamana pa ni?

Ọgbẹni J. Edgar Hoover ti n ṣiṣẹ ni ile iwadi ohun gbogbo ti apapọ ilu Amẹrika wi pe, “A ko le fi opin si iwa buburu nipa jijẹ awọn ọdaran niya. A kọkọ gbọdọ pada si ṣiṣe abojuto igba èwe ki a to le ṣe atunṣe ibalopọ ẹgbẹ́-ọ̀gba.” Lakoko yii awọn ti ọjọ ori wọn kò i ti tó ogún ọdún ni o pọju ninu iye awọn ọdaran.

**Anfaani Ile-ẹkọ Ọjọ Isinmi**

Bi o tilẹ jẹ pe taba mimu, kika iwe ti kò dara ati ẹgbẹ buburu maa n ṣi eniyan lọna, ile-ẹkọ Ọljọ Isinmi a maa tọ ni sọna ti o dara. Aimoye ọkẹ awọn ọmọde ni orilẹ-ede wa ni a kò fi ẹkọ Bibeli kọ́. Bi iwọ ba jẹ ọmọkunrin tabi ọmọbinrin ti o n lọ si ile-ẹkọ Ọjọ Isinmi, o gbọdọ maa dupẹ lọwọ Ọlọrun fun anfaani yii, o si yẹ ki o mọ iriri olukọ rẹ ti o n sa gbogbo ipa rẹ̀ lati ràn ọ lọwọ lati sá asala kuro ninu “ere ẹṣẹ.” A ni lati gbiyanju ki a mu awọn ọmọkunrin ati awọn ọmọbinrin miiran wá si Ile-ẹkọ Ọjọ Isinmi. Ẹ má ṣe jẹ ki a kuna lati ri erè Onigbagbọ gbà, ẹbun-ọfẹ Ọlọrun, “iye ti kò nipẹkun, ninu Kristi Jesu Oluwa wa.”

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni itumọ ki a “da ni lare”?
2. Ki ni itumọ “oore-ọfẹ”?
3. Ki ni Ọlọrun ṣe fun wa lati fi ifẹ nla Rẹ̀ han?
4. Darukọ ọna kan ti a le gbà san an pada fun Un lọna kekere.
5. Ẹsẹ wo ni o n kọ́ wa ninu ori kẹfa pe Onigbagbọ́ ki i dẹṣẹ?
6. Ẹrú ta ni ẹlẹṣẹ i ṣe?
7. Ta ni i ṣe olori fun Onigbagbọ́.
8. Ṣe afiwera erè ẹlẹṣẹ ati erè Onigbagbọ́?
9. Iwọ ha ro pe ó lere lati sin Oluwa? Ki ni ṣe?
10. Ẹsẹ wo ni o n kọ́ wa nipa isọdimimọ́ ninu ori kẹfa?